# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

## Idahun Si Ibere Yakubu Akanbi (1)

Olotu, jowo gba mi laye lati dahun si ibere Ogbeni Yakubu Akanbi, Kumasi G.C. eyiti o bere ninu Iwe Irohin Yoruba ti 10.8.53 nipa eran pipa.

Ki ise ewo fun Onigbagbo lati ma gbe le eran Ileum. Kakańe, Bibeli pase fun wa ninu Lefitiku 17:13, pe :- "ati enikeni ninu awon omo Israeli, tabi ninu awon alejo ti nse atipo ninu won, ti nse ode, ti o si mu eranko tabi eiye ti a o ba je; ani ki o ro eje re danu, ki o si fi erupe bo o."

"Kiki eje ni enyin ko gbodo je; lori ile ni ki e da a si bi omi."-Deuteronomi 12:16.

Enikeni le pa eran; ohun ti o se pataki nipe ki a ro eje etan na si'e, ki a si fi erupe bo o.

Emi ni, &<br>
E. K. Akinlade

ILARO

## Idahun Si Ibere Yakubu Akanbi (2)

Mo ki nyin pupo ni oruko Oluwa, e ku ise, Oluwa yio f'ere si ise nyin o, amin. Inu mi ndun ni nigbati mo ba nka Iwe Irohin Yoruba nyin, mo si ki nyin pupo fun opo laala ti e nse lori Iwe na, ki Oluwa ki o ran nyin lowo.

Ese ibere Ogbeni Yakubu Akanbi Kumasi G.C. ti o jade ninu Iwe Irohin Yoruba ti 10.8.53 pe Onigbagbo ko gbodo pa eran tabi dumbu eran ni?

Mo dupe pupo lowo Ogbeni na. Ki nse pe Onigbagbo ko gbodo pa eran tabi dumbu eran ni, Ojigbon nitoripe awon Imale kifi je eran ti Onigbagbo ba pa; beni opo Onigbagbo si o ni (...) lo je Imale. Opo awon alamokan lo korira Igbagbo, awon Imale ka eran ti Onigbagbo ba pa si gifa beni asiro ati asise lo je, awon Imale nje eran igbe Iorisirisi, eja palapala tabi awon eran bebe lo, Feni awon ode (Hunters) to ndigbe pa eran, opo won ni o je keferi, to se pe ki o to lo sode yio bo Ogun re ko si ni kewu. Awon ti o npa eja ki i kewu si i bi o ba se be nwon ki ba ti je awon eran ati eja ti a daruko wonyi.

Ki ise gbogbo Onigbagbo lo mbo awon Imale loran pa afi awon ti ko pe ninu isin won, nitoripe ohun ti oro Olorun so fun wa nipe ki a mase je oku eran tabi eyiti a ba lo lorun pa. Ohun ti Olorun mbere lowo wa ni iwa mimo ki ise pe nigbati a ba je eran ni a di alaimo, tabi nigbati a ko ba je e ni a di eni mimo. Iwa mimo, ni Olorun mbere lowo wa.

Olotu mo dupe fun aye ti e gba mi. Oko Oba ko ni se nyin lese o.

Emi ni,<br>
D. O. Adediji.

IBADAN

### AKIYESI

Idahun si ibere Ogbeni Yakubu Akanbi ti awon Ogbeni G. Bolariwa ti Ibadan, J. A. Ogun'ade ti Eko ati ti E. O. Assolaiye ti Kumasi G.C. fere dogba pelu idahun ti Ogbeni D. O. Adediji dahun si ibere na, iyen ni ko je ki a tun te won jade ni eyo yi mo. E ku ise o. Abukun Oluwa.

OLOTU




## Ogbeni Salami Adeoti Gbe Iyawo

OMU-ARAN— Iesuuloyi ni Ogbeni Salami Adeoti gbe Omidan Omolape Elepinjoree ni iyawo alarinrin, irohin ko to amojuba re, iru igbeyawo na ko sele ri ni ilu Omu - Aran. Egbe Onisowo Pako (Planks Sellers) se bele lojo na, ese gbogbo egbe pataki - pataki ati awon pataki - pataki ni o pe si ibe, oko iyawo na si fi orisirisi onje adidun ati orisirisi oti ati siga e gbogbo awon alabapere ojo na loran, ijo ati ayo ojo na gadabu.

Die ti aye wa fun lati daruko ninu awon alabapere ojo na ni awon Ogbeni Lawani Dosumade, Sunmonu Adedeji, Ezekiel Baba - Isale Ijo C. M. S. Omu-Aran, S. Ade. Aransiola, Salami Bamigbola, ati J. B. Buoye. Ki Olorun fi ibukun si igbeyawo na ki O si fi Omo rere sike Iyawo o.


# Atura Ipara Ti O Yanilenu

O ntun awo-ara se

O nmu Irora kuro

O si nle gbogbo Otutu lo



Sa Ma Fi Paa

"Mentholatum" je ipara ti o ntun ara enia se bi idan. Bi ara ba ndun e, bi o ba ni efori tabi irora, tabi ti otutukotuto lo ba eyo e lenu, "Mentholatum" ni ero re. O nrorun pupo lati lo, yio si sise bi idan, sa fi pa ibi ti o ndun e. A je bi idan ni "Mentholatum". On ni o dara ju gbogbo egbogi ipara lo. Tete lo ra ide tabi agolo re kan loni.

Bere Fun Mentholatum



O wa ninu agolo ati ide

Awon "The Mentholatum Co. Ltd., Est. 1889 Slough, England nikan ni nwon nse e.

MENTHOLATUM



## WA FUN IWOSAN !

### ILERA L'OOGUN ORO

Enikeni ti arun wonyi ba nba a ja ki o wa si odo mi ma a si se iwosan re pelu egbogi ti yio le e lo patapata.

Iru arun bawonyi:-

1 ESE-ORUN—Nko ni la a rara tabi ki nfi ogun san an ki nto wo o san
2 ORI-YIYI tabi SIWERE—Mo le wo o san patapata,
3 WARAPA
4 OBIRIN TI IPONJU AIRI OMO BI BA MBA A JA - Ki o ma a bo Oluwa yio fun ni omo rere.
5 KOKORO OYAN—Emi yio yo kokoro na ni ojo kanna ti o ba wa
6 Oju sisu tabi eniti ko ba riran daradara, ki o wa, ma a wo o san tan patapata
7 Obirin ti ko iti damgbo ti ko ri nkan osu re mo ki o ma a bo yio si ri iwosan
E wa dan mi wo ki e si ridi oro.

Lawani Maiyegun<br>
(OLORI ONISEGUN)<br>
3, IKOYI ROAD (Obalende) LAGOS.



Eyi ni aworan awọn Ọba Adele, Keji, Dokita Akinọla Maja, Ewusi Makun ati awọn Oloye miran pẹlu Ọlọla ati Iyaafin Ọbafẹmi Awolọwọ ni Ebute Ọkọ Ofurufu Ikẹja nigbati awọn gunlẹ lati Ile Oyinbo.

No. 102.

## RADIO DISTRIBUTION SERVICE, LAGOS.

As from the 1st October, 1953, the distribution of Radio Programmes over the Posts and Telegraphs System will close down with the exception of the service to subscribers in IKOYI.

2. In the IKOYI area the Posts and Telegraphs Department's loudspeaker boxes will continue in service until further notice.

3. Anyone who wishes to rent a loudspeaker box in other areas should apply to Rediffusion (Nigeria) Limited at any of the following addresses:

(i) Rediffusion House,
Clifford Street,
EBUTE—METTA.
(ii) No. 108 Tokunboh Street, Lagos.
(iii) Agege Motor Road, Idi—Oro.

(Sgd.) P.A. COURTNEY,
DIRECTOR OF POSTS AND TELEGRAPHS.


# Tete Wo Iko Re San




Bi ikọ ba nfin ẹ ni ọnaọfun ti ko si jẹki o san lalẹ, mu iwọn iba Veno's diẹ ki o to sun.

Ti o ba di ẹ ni aiya ti o si fun ẹ ni iolra, mu Veno's, lẹsẹkẹsẹ ni wa ti ri irọrun ati itura.

Bi o ba ti d'ọgbẹ ti ẹ ni ọna ọfun, gbogbo rẹ ni Veno's yio mu kuro pẹlu irọrun.

Fi Veno's si arọwọto rẹ fun lilo awọn ọmọ ati aya rẹ, iba ṣe ẹmẹde tabi agbalagba. Tete lọ ra igo kan loni.

SA MU

VENO'S LIGHTNING COUGH MIXTURE


## Situ Adedeji Sin Ọmọ F'oko

BOMIKARA G. C.—Ni ọjọ lẹtgun ti ise ọjọ kọkanla osu kijọ ọdun yi ri Ọgbẹni Ṣitu Adedeji sin Ọmọ re Omidan Ọlayẹnu Arinpe fun ọkọ rẹ.

Lati igbati ọjọ 'sin igbeyawo na ti ku ọjọ mẹfa ni ẹsẹ awọn ọmọlẹbi ti pe si ọdọ Baba iyawo, nwọn si bẹrẹ owo rina titi Ọjọ Faaji na fi pe.

Enu kọ Irohin ni inawo ọjọ na. Iya iyawo Sẹlia Ẹyinọsun fa ọmọ yọ ni ọjọ na, bi nwọn ti ngmule pọnti, bẹni nwọn ngmu ọna pọnka, a ko tilẹ mọ iru eyiti a le mu ninu oriṣiriṣi ọti ti nwọn ngbe kalẹ. Ilẹ e na si ni oriṣiriṣi akara aladidun. Gbadamọsi Owolabi ṣe gudugudu meje ni Ọjọ Faaji Ọmọ na, Efin siga dabi igbati Ọkọ reluwe aba mbọ a ko tilẹ le tun ma so ti obi mọ.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn alabaṣẹye ọjọ na ni yi Gbadamọsi Owolabi, Thomas Ojo, Rufus Adebinpe, Joshua Atuoye, Jinadu Adeleke, Israel Adewọyin, Ṣitu Toye, Muniratu Azikẹ, Ayi Alari.

Ki Edumare fi ayọ kari gbogbo wa o ki O si ṣe iyawo na ni abiyamọ. Ase.

## Omo Nigbe Enia Niyi

EKO—Ni ọjọ Aje ti nse ọjọ keje osu yi ni Ọgbẹni I. A. Banwo ṣe ikomọ ọmọ obirin rubutu ti Iyawo rẹ, Iyaafin Sinatu Banwo bi fun un ni ọjọ kokanlelogbọn osu tokọja yi ni nile rẹ 71, Bamgboṣe Street l'Eko.

Irohin ko to amojuba ni onjẹ ati ọti ti baba ọmọ pese fun awọn ọrẹ, ojulumọ ati gbogbo awọn alabaṣẹyẹ na. Ajẹti ati amuti ni nwọn si fi onjẹ ati ọti ọjọ na ṣe.

A dupẹ lọwọ Ọgbẹni M. A. Olowoagbo oṣiṣẹ Amalgamated Press aburo baba ọmọ na fun inawo ọjọ na, o ṣe gudugudu meje ni ọjọ na.

A sọ ọmọ na ni Oluwarẹmilẹkun, Oluwatoyin, Adiatu, Aṣakẹ.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn ti o wa nibi isọmọ - loruko na ni yi: Ọgbẹni Raji Adeleke, M. A. Ṣoetan, S. S. Kọlasade, A. Ogunkoya, S. Yusufu, R. T. Podo, Capt. D. B. Banwo, Raimi Bamgbopa, Otunẹhinwa, A. Bamiro, Nasiru Ajasa, J. T. Alagba, awọn Iyaafin Ayisatu Williams, Muniratu Balogun, Silifatu Kọlasade, Funmilayọ Alagba, Suwebatu Ajaṣa, Juliana Ariyọ ati Funmilayọ Osinde.

## Egbe Ifelodun Se Ikomo

ANYINAM G. C.—Ni ọjọ kẹwa osu keje ọdun yi ni awọn Ẹgbẹ Ifẹlodun wa ba Olori Ẹgbẹ wọn Ọgbẹni Tiamiyu Oyewunmi, ọmọ Ile Aworo Oshogbo ṣ ikomọjade ọmọkonrin kan ti Olọrun fi ta on ati aya rẹ Fatumọ lọrẹ ni ọjọ kẹta osu na.

Alfa Suberu Akanni ọmọ Ilorin ni o ke hutuba isọmọloruko na ni Aṣẹ Ọlọrun ati ti Anọbi rẹ o si sọ ọmọ na ni Abudu 'Kasiliyu Oyewunmi.

Lẹhin eyi ni Baba ọmọ na wa ko oriṣiriṣi onjẹ silẹ, Ẹhin onjẹ, ọti oriṣiriṣi, bẹ e ni awọn onjẹ ti awọn ngmu titi ilẹ fi ṣu ti ilu sakara ndun pẹlu oriṣiriṣi orin ayọ.

Alufa Bello Adegun ọmọ Ile Awero, Oshogbo. Ẹgbẹ na baba ọmọ na nawo papọ, bẹna na ni awọn Ọgbẹni D. B. Owolabi, Aṣoju Iwe Irohin Yoruba, Bello Aderọgba, Lawani Ẹgbetọla, Alufa Lawani, Salami Afọlabi, Gbadamọsi Ogunbọde ati Lawani Adefore.

Awọn Ẹgbẹ Ifẹlodun ṣe are pupọ ni ọjọ na, ẹsẹ gbogbo wọn ni o si pe si bẹ, awọn ọmọ Ẹgbẹ na ti pọ ju pe ki a ma a daruko wọn lọkọkan lọ. Ki Oluwa da ọmọ na si, ki O si fi ire kari o.


E ma a polowo Oja nyin sinu Iwe

Irohin Yoruba

E o si ri iyatọ larin bi ẹ ti si ni Ọnibra si i ati bi ẹ o ti tun bẹrẹ si ni i si nisisiyi.


Printed And Published By The Service Press Limited
5 & 7 Apọngbọn Street Lagos.